Wọn pa mi laṣẹ ki n fi ori kan'lẹ lori oríkèé meje

Lati ọdọ ọmọ Abbās - ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji - lati ọdọ Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - o sọ pe: «Wọn pa mi laṣẹ ki n fi ori kan'lẹ lori oríkèé meje: Lori iwaju ori, o si na ọwọ rẹ si imu rẹ, ati ọwọ mejeeji, ati orunkun mejeeji, ati awọn ọmọ ika ẹsẹ mejeeji, ati pe ki a ma ka awọn aṣọ ati irun».

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ṣe alaye pe dajudaju Ọlọhun pa a laṣẹ nibi irun ki o fi oríkèé meje ninu awọn oríkèé ara rẹ kan'lẹ; awọn naa ni: Alakọkọọ: Iwaju ori: Oun ni: Alawẹ oju ti o wa ni oke imu ati oju mejeeji, Anabi, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun o maa ba a, fi ọwọ rẹ si imu rẹ, ti o fihan pe iwaju ati imu jẹ ọkan ninu awọn meje naa, o si tẹnumọ pe ẹni ti o n fi ori kan ilẹ maa fi kan ilẹ pẹlu imu rẹ. Oríkèé kejì ati ìkẹta: Ọwọ mejeeji. Ẹlẹẹkẹrin ati Ẹlẹẹkarun-un: Orunkun mejeeji. Ẹlẹẹkẹfa ati Ẹlẹẹkeje: Awọn ọmọ ika ẹsẹ mejeeji. O si tun pa wa laṣẹ ki a ma so awọn irun wa, ki a si ma ka awọn aṣọ wa papọ nibi iforikanlẹ lati fi da aabo bo o; bi ko ṣe pe a maa da a silẹ titi ti yio fi kan ilẹ, nitori naa yio le'lẹ pẹlu awọn orikee ara naa.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/10925